Changing the World One Smile at a Time

# Àwọn Ìmọ̀ràn Fífúnni lóúnjẹ ti Smile Train fún àwọn ọmọ tó ní Ètè àti Òkè ẹnu tó pín sí méjì

**1** **A bí àwọn ọmọ kan pẹ̀lú ẹnu tó pín sí méjì –** ihò, ààyè, tàbí àlàfo nínú ètè wọn tàbí ihò ní òkè ẹnu wọn (èyí tí ó lè má hàn láti ìta).



**2** **Iṣẹ́-abẹ ṣe pàtàkì púpọ̀** nítorí láìsí èyí ọmọ náà lè má lè sọ̀rọ̀ dáradára, ó lè wà lábẹ́ ewu àwọn oríṣiríṣi àkóràn, ó sì lè ní ìṣòro láti jẹun tàbí láti mu wàrà.



**3** **Dọ́kítà oníṣẹ́-abẹ ti Smile Train lè ṣe àtúnṣe sí àlébù yìí lọ́fẹ̀ẹ́** ní ilé-ìwòsàn aláàbáṣiṣẹ́pọ̀ Smile Train. Iṣẹ́-abẹ nìkan ni ọ̀nà tí a lè gbà ṣe àtúnṣe sí àlébù yìí lẹ́kunrẹ́rẹ́.



**4** **Láti lè wà ní àlàáfíà, àti láti lè** ní okun nínú tó fún iṣẹ́-abẹ, ó ṣe pàtàkì kí a fún àwọn ọmọ-ọwọ́ tó ní ẹnu tó pín sí méjì ní oúnjẹ tó péye.



**5** **ṢÙGBỌ́N – nígbà mìíràn, a má a ṣòro fún àwọn ọmọ-ọwọ́ tó ní ẹnu tó pín sí méjì láti jẹun** nítorí wàra lè má a jáde láti imú wọn tàbí kí ó sá pá wọn lórí. Tàbí ọmọ-ọwọ́ náà lè má a fa atẹ́gùn sínú, ó sì lè dàbí pé wọ́n yó, kí wọ́n sì sùn lọ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọn kò tíì fa oúnjẹ tó tó.



**6** **O ṣe pàtàkì pé kí ọmọ jẹun dáradára kí a bá a lè ṣe iṣẹ́-abẹ fún un.** Ìyá gbọ́dọ̀ mú u bí ojúṣe ara rẹ̀ láti dán àwọn oríṣiríṣi ìlànà ìfọ́mọlóúnjẹ wò, láti lè mọ ìlàna tó wúlò jùlọ fún òun àti ọmọ rẹ̀. Ó dára púpọ̀ jù láti fún ọmọ ní wàrà tààrà láti inú ọyàn, bí ó bá ṣe é ṣe. Àwọn ìlànà kan ní:



Jẹ́ kí ọmọ náà jókòó sókè bí ó ti njẹun.



Gbé orí ọyàn sí apá ibi tí ẹnu ọmọ náà kò ti gé.



Rọra tẹ ọyàn láti mú kí wàrà náà lè jáde dáradára síi.



Má a fún àwọn ọmọ bẹ́ẹ̀ lóúnjẹ nígbà púpọ̀, kí o sì má a jẹ́ kí wọ́n gùfẹ̀.

**7** **Bí fífún ọmọ náà ní ọyàn kò bá ṣe é ṣe,** ó ṣe pàtàkì fún ìyá rẹ̀ láti tẹ̀síwájú láti má a fún ọmọ náà ní oúnjẹ ní ọ̀nà mìíràn. Irú àwọn ọ̀nà bẹ́ẹ̀ ni:





Ìyá lè tẹ wàrà jáde láti inú ọyàn láti fún ọmọ náà pẹ̀lú ṣíbí tàbí ìgò ìfọ́mọlóúnjẹ.



Ìyá lè fẹ ojú ihò ara rọ́bà ìdérí ìgò ìfọ́mọlóúnjẹ DÍẸ̀ láti mú kí wàrà lè má a jáde dáradára síi.

**8** **Bí kò bá sí ọyàn rárá,** ìyá lè lo wàrà màlúù tàbí àkànṣe wàrà málúù fún àwọn ọmọ-ọwọ́. Ríi dájú pé wàrà màlúù àti omi fún pípo àkànṣe wàrà màlúù náà hó lórí iná, kí ó sì tutù díẹ̀.








**9** **Ríi dájú pé àwọn ohun èlò yòówù tí a fi nfún ọmọ ní oúnjẹ wà ní** mímọ́, kí o sì sè é nínú omi tí nhó lórí iná fún, ó kéré jù, ìṣẹ́jú 10. Ṣíbí àti ìgò ìfọ́mọlóúnjẹ tí kò mọ́ lè fa ìgbóná àti àkóràn.



**10** **Jọ̀wọ́ máṣe gbàgbé láti gbé ọmọ rẹ lọ sí ibùdó Smile Train tó wà nítòsí rẹ.** Dọ́kítà kan ní ibùdó náà yóò ṣàyẹ̀wò ọmọ náà, yóò sì sọ fún ọ àkókò tó yẹ kí o wá sí ilé-ìwòsàn fún iṣẹ́-abẹ.

Rántí, gbogbo ìtọ́jú ní ibùdó Smile Train yòówù jẹ́ ọ̀fẹ́ pátápátá.




